Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras
São Francisco do Conde (BA) | vol. 5, nº Especial I | p. 249-251 | jan./ jun.2025.

# Ta Ló Lè Ṣe É?

**Báyọ̀ ỌMỌLỌLÁ** *
ORCID iD https://orcid.org/0009-0007-0650-7805

Èèyàn lásán ò le wá'kọ̀ ilú

Kọ́kọ́ ó má fẹṣẹ̀ lù,

Kí táyà ó má ta pàú,

Kárá ìlú ó má fariwo bọnu

Bí ẹni wọn só pa,

Bí ẹni rìngbẹ́ tó lu pákùté onígán láìròtì

Tó fò sókè

Tó jan'ra ẹ̀ mọ̀lẹ́

Tó ń dúnra

Tó wọ̀tún wòṣì

Tí ò rẹ́nì kan

Tó ké ké ké

Tó sun sun sun

Tí ò lè gbara ẹ̀ sílẹ̀,

Tóró irin ń ṣe kíṣà fún lẹ́ṣẹ̀

Tó tọra,

Tó ń làágùn yọ̀bọ̀

Bí ẹni ọwọ́ dùnníbi ìjá ẹkẹ

Bí ẹni wọn ń nà tí ò lè gbọ́wọ́.

Ti kasan ọ̀rùn rẹ̀ yọ wanwa

Tó nàró sí lọ́rùn láìṣèlẹ̀kẹ̀ tá a fi ń ṣẹ̀ṣọ́.

Tóró pákúté ń mú kíkankíkan

Tó wá ń hàn bíi gàté télùbọ̀ wàǹkòkò di wankoko mọ́ lọ́fun

Tó ń jìjàdú kò lè bọ́ nínú ìnira.

Èèyàn lásán ò le wá'kọ̀ ilú

---

* Department of Languages and International Studies, Morgan State University, Baltimore, Maryland, USA. E-mail: bayo.omolola@morgan.edu

Kọ́kọ́ ó má fẹṣẹ̀ lù,
Kí táyà ó má ta pàú,
Kárá ìlú ó má fariwo bọnu
Bí ẹni wọn só pa.

Èèyàn tó yán ló lè dá nǹkan gidi láṣà
Tí ò ní lè fẹṣẹ̀ káṣá
Táyé ó ní fẹnu ṣátà
Kí wọn ó máa kàn lábùkù kágboro
Bí àgbò tó ń ṣàìṣán
Tó ń tọ̀gbẹ́
Tó lóun lòun lè w'ará ìlú sàn
Kóhun ó gbà wọ́n sílẹ̀ nínú àárẹ̀.

Eégún tí yóò jóóre,
Ìgbéṣẹ̀ rẹ̀ là á tii mọ̀.

Èèyàn lásán ò le wá'kọ̀ ilú
Kọ́kọ́ ó má fẹṣẹ̀ lù,
Kí táyà ó má ta pàú,
Kárá ìlú ó má fariwo bọnu
Bí ẹni wọn só pa.

Èèyàn tó yàn lá bá wá
Káyé ó lè rójú,
Kílùú ó sì dẹ̀rọ̀.

Níbo lèèyán gidi wà o jàre?

Ká fọwọ́ lu pẹpẹ
Kí pẹpẹ ó lu;
Ká fọwọ́ lu àjà kájà ó jìn;
Ká náwó ìlú,
Kẹnu ó rin sìnkìn

Ká fàkà sìnkín múkọ gbogbo ìlú.
Ebi ò báà fọ́jú ará ìlú ló kúnnú olóṣèlú.
Ẹni tó dára nínú wọn kò tó nǹkan.

Ẹ má sì mí gbọ́.
Odò l'àwọn olóṣèlú wa.
Ó kàn jẹ pé èéwù pọ j'omi tó mọ́ geere lọ ni.

K'áwa ará ìlú kọ́gbọ́n,
Ká wá adámi tí ó módò tòró,
Ká má baà mèéwú mọ́.
A ti ń ṣe múgùn pẹ́,
Nǹkan ò sì rọgbọ.
Ó yẹ ká ti kọ́gbọ́n,
Ká gbọ́n,
Kágbọ́n èèyàn lásán l'ágbo olóṣèlú yéé ta wá.

Èèyàn lásán ò lè ṣèlú;
Èèyàn tó yàn ló lè da'bi kó yàn-àn-àn.

Recebido em: 23/02/2025
Aceito em: 24/06/2025

**Para citar este texto (ABNT):** ỌMỌLỌLÁ, Báyọ̀.Ta Ló Lè Ṣe É? *Njinga & Sepé:* Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras. São Francisco do Conde (BA), vol.5, nº Especial I, p. 249-251, jan./jun.2025.

**Para citar este texto (APA):** Ọmọlọlá, Báyọ̀. (jan./jun.2025). Ta Ló Lè Ṣe É? *Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras.* São Francisco do Conde (BA), 5 (Especial I): 249-251.